Nnkan kan ko nii ṣẹlẹ si Musulumi ninu wahala ati aisan ati ironu ati ibanujẹ ati suta ati ironu ati ki ẹgun gun un afi ki Ọlọhun ba a fi pa awọn aṣiṣe rẹ rẹ

Lati ọdọ Abu Sa'eed Al-Khudriy ati lati ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji- lati ọdọ Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- o sọ pe: "Nnkan kan ko nii ṣẹlẹ si Musulumi ninu wahala ati aisan ati ironu ati ibanujẹ ati suta ati ironu ati ki ẹgun gun un afi ki Ọlọhun ba a fi pa awọn aṣiṣe rẹ rẹ".
[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n ṣàlàyé pe dajudaju ohunkóhun tí ó bá ṣẹlẹ̀ sí Mùsùlùmí, bii aisan ati ironu ati ibanujẹ ati ajalu ati ile koko ati ipaya ati ebi- koda ki o jẹ ẹgun ni o gun un ti o wa n ko inira ba a-, ìyẹn maa jẹ ipa ẹṣẹ rẹ fun awọn ẹṣẹ rẹ ati awọn aṣiṣe rẹ.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3701